


# Irohin Yoruba

NO. 768 | FEBRUARY 24 — MARCH 1, 1960 | Kobo Meji (2D.)


**LAKAYE ORỌ**

OJU Oluwa mbẹ lara awon olododo, eti Rẹ si ṣi si igbe won. Oju Oluwa kan si awon ti nṣe buburu lati ke iranti won kuro lori ile.

Awon olododo nke, Oluwa si gbọ, o si yọ won jade kuro ninu isẹ won gbogbo.

# ỌBA'BIRIN GẸẸSI TUN BI ỌMỌKUNRIN

LỌNDỌNU.

NI deede agogo mẹta abọ (ti iṣe agogo mẹrin abọ ti Naijiria) ọsan ọjọ Ẹti ni Ọlọlajulọ Ọba Alaiyeluwa Elizabeth Keji, Ọba'birin Gẹẹsi bi ọmọkunrin kan kun awọn ọmọ meji, Charles ati Anne ti o ti bi tẹlẹri.

Lẹhin ọgbọn iṣẹju ti o bi ọmọ na ni nwọn se ikede rẹ fun gbogbo ilu gbọ pe "Ọba'birin Gẹẹsi bi ọmọkunrin kan". Ki o to di pe o bi ọmọ na, awọn ọgunlọgọ enia ti duro si ita iwaju Afin lati igbati o ti nrọbi, gbogbo enia si ho fun ayọ ibi ọmọ na.

Nitoripe ọmọ titun ti Ọba bi na jẹ ọkunrin, o wa ni ipo keji lati jẹ Ọba, ẹgbọn rẹ Anne ti nwọn si bi i le, nitoriti o jẹ obirin, o si wa ni ipo kẹta, aburo Ọba ọmọbirin Ọba Margaret si wa ni ipo kẹrin nisisiyi gẹgẹbi eto a ti gori Itẹ Ijọba Gẹẹsi.



ba'birin Gẹẹsi Elizabeth Keji

## Ina jo Ọba ti Ijọba Ariwa rọ loye pa

BAUCHI.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidilogun oṣu yi ni Ọba Darazo, Malam Ibrahim Hanza, eni ọdun marun le ladọta, ti Ijọba Ipinlẹ Ariwa rọ loye, ti nwọn si le kuro ni ilu, ku si inu ina ti o jo ile ti o gbe ngbe ni abule Soro lẹba Bauchi.

Jamba ina yi ṣẹlẹ ninu ile koriko ti Ọba yi ngbe lati igbati nwọn ti le e kuro ni ilu rẹ, ni oju orun ni ina na ba Ọba yi, awọn enia meji ti nwọn mba a gbe ile si sare jade lai fi ara pa nigbati ina na bẹrẹ, bi nwọn ti gbe Ọba na de ile Iwosan ni o ku. Nwọn si ti sinku rẹ na si Bauchi.

## Iyawo Ọmọ-Ọba Swedeen bẹ Ẹko wo



Aworan yi ni ti Ọlọlajulọ Ann Bernadotte, aya Ọlọlajulọ Ọmọ-ọba Carl Bernadotte, ọmọ ẹgbọn Ọba Ilu Sweden ati ti Ọgbẹni S. O. Shonibarẹ, Alakoso Agba ile-iṣẹ 'Amalgamated Press of Nigeria Ltd.' ti o ngba a lalejo nigbati o wa bẹ awọn ile-iṣẹ "Daily Service" wo lenulọlọyi.

Ẹniti o tẹle e na ni Iyaafin Solberg, aya gbajumọ onisowo kan l'Ẹko. Aya Ọmọ-ọba na si ba Ọgbẹni Frank Tosh, 'Technical General Manager' jomitoro ọrọ nigbati o lọ wo irin-iṣẹ itẹwe( Printing Plant) ibiṣẹ na wo fun aṣeko diẹ ki o to ma a lọ.

## Awọn Ẹgbẹ Ogbomọshọ Parapọ Ile ṣeyẹ fun Akintọla

OGBOMỌSHỌ.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidilogun oṣu yi ni awọn Ẹgbẹ Ogbomọshọ Parapọ ti ilu Ogbomọsho paapa pe ase apejẹ ajọyọ ikini kuorire kan si Gbọngan Apejọ Ṣọun ni Ogbomọshọ fun Oloye S. L. Akintola, Aṣipa Ogbomọshọ, Gbakeji Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lati ba a yọ ayọ lori ipo Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ti o bọ si.

Lẹhin sisi ipade apejẹ na, nwọn si fun un ni Iwe-Ayẹsi ikini-ku-orire. Ninu Iwe-ayesi na ni nwọn ti so pe, awọn ọmọ Ẹgbẹ Ogbomọshọ Parapọ dupẹ gidigidi lọwọ Oloye Akintọla fun wahala ati aayan ti o ti ṣe ti o si tun nṣe sibẹsibẹ fun itankalẹ ẹgbẹ na kakiri ilu Naijiria ati Ghana (Oke-Okun). Awọn si tun dupẹ lọwọ rẹ fun ijakadi ti o ja pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ fun idagbasoke gbogbo awọn ilu Naijiria.

Nwọn tun ṣe apejuwe ninu iwe-ayesi na pe, ojulowo ọmọ Yoruba ti o n'ẹkọ-ijinlẹ nipa ede Yoruba ati ọlaju ilẹ Yoruba ni Oloye Akintọla, nwọn si bẹ ẹ pe ki o lo ọgbọn iṣẹ olukọ rẹ ṣe akojọ awọn iwe itan ilẹ Yoruba, awọn owe ilẹ Yoruba ati awọn alọ ilẹ


Wo oju ewe kẹrindinlogun


## Ẹka Ẹgbẹ Alakukọ ni ki Azikiwe fi ipo Olori Igbimọ Agba Oṣelu silẹ

NI ọjọ Abameta ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni awọn Ẹka Ẹgbẹ Alakukọ "The Zikist National Vanguard" se ipinnu ti nwọn si ṣe ikede rẹ fun gbogbo enia pe nwọn ko fẹ Dọkita Nnamdi Azikiwe Olori Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni Olori Igbimọ awọn Agba-Oṣelu (President of the Senate) mọ. Nwọn ni awọn fẹ ki o fi aye na silẹ kiakia, ki o si fun jẹki nwọn dibọ fun on wọle Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ti nwọn ti dibo fun un wọle ni ọjọ kejila oṣu kejila ọdun ti o koja ti o si fi aye na silẹ nitori ti nwọn yan an ni Olori Ajọ Igbimọ awọn Agba-Oṣelu.

Nwọn ni idi ti awọn fi fẹ ki o fi ipo na silẹ ni pe, ki iṣẹ ipo tio yẹ e rara nitori awọn ko fẹ ki o fi isimi igbekun yọwọ kuro ni ọran Iselu, nitori aye ti o wa ni isisiyi dabi ẹniti o wa ninu igbekun isimi kuro ninu ọran iṣelu, ati pe awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakuko ti o wa pẹlu Ẹgbẹ Olomi (NPC) ti nwọn jijọ fi ọwọ-sowọpọ se Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria kan wa ni ibẹ bi agutan ti ko ni olusọ ni. Nitorina ki Azikiwe tete fi ẹsẹ ẹhin de ile, ki o lọ fi orukọ silẹ lati tun dije wọ Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria.

Nwọn ni pipapọ ti nwọn papọ-mọ Ẹgbẹ Olomi (NPC) ṣe Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria dabi enipe gbogbo isẹ ti awọn Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti nṣe lati ẹhin bọ wa, Ẹgbẹ Olomi (NPC) ni o wa ko gbogbo ere rẹ. Nwọn ni Ẹgbẹ Olomi (NPC) ti o jẹ wipe nipa tita abuku fun awọn Ẹgbẹ Oṣelu Isalẹ Ọya (South) ni nwọn fi ṣe ẹsin ọrọ ipolowo Ẹgbẹ wọn fun ikede idibo wọle ni Oke-Ọya nipa didi ẹsin Imale mu fi tako awọn miran t lo si jẹ pe nwọn ko ṣegun idibo na koja Ipinlẹ


Wo oju ewe kẹrindinlogun

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Oku Ọlọmọ gẹgẹ la o gbe e

OWODE.

AGBỌJUGBANU ni iku baba wa Petera Sotayọ Sorunmu, ẹni ọdun mọkandiladorin, ti o sinmi ninu Oluwa ni ale Ọjọru ọjọ kẹfa oṣu yi ni ile rẹ ni Adugbo Ọbafẹmi ni ilu Owode.

A ṣe isinku ologbe na ninu Ile Ọlọrun ni Owode. Ọgbẹni N. B. Falanọ ẹniti o ṣe isin isinku na yin ologbe na wipe o jẹ Onigbagbọ ododo.

Ologbe yi jẹ ọmọ ologbe Ṣorunmu Apena Imọ, obi ọpọlọpọ ọmọ, lọkunrin ati lobirin, o si fi iyawo meji silẹ ninu awọn ọmọ rẹ ni Iyaafin Wuraọla Ọrẹdẹin iyawo akọwe agba Ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Diẹ ninu awọn enia pataki ti o wa si ibi isinku na ni Ọgbẹni S. T. Ọrẹdein ati aya rẹ, Ọgbẹni Lawani Daodu lati Ṣagamu, Ọlọla J. A. O. Ṣobọla, Ọgbẹni L. A. K. Ogunwọlu, Ọgbẹni Sam Onafadeji ati Iyaafin Comfort Akigbogun.

Awọ enia ti o tẹle ologbe na de Boji le ni ẹgberun meji. Ki Ọlọrun ki o fi ọrun kẹ. Ki Ọlọrun jẹki ọjọ jinna si ara.

## Isin Ijade oku Bisọbu William dun

IFỌ

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni awọn Ijọ Soọsi Afrika ti Oju Sango ni agbegbe Ifọ ṣe ijade oku Eni-Ọwọ Bisọbu Charles Hayes Williams, ẹniti o jalaisi ni ọjọ kẹtala oṣu kejila ọdun ti o kọja yi. Bisọbu M. O. Ọdẹrinde lati Ọwọ ni o ṣe iwasu n'ibi isin na, o si sọ ọrọ nipa iṣẹ rere ti ologbe na ṣe, ati bi o ti jẹ olufọkansin to nigba aiye rẹ. Ọpọlọpọ awọn enia pataki ni o wa si ibi isin-iranti ologbe na.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ni awọn Ẹni-ọwọ Primate E. M. Olulode, Bisọbu J. P. Jiboku, E. A. Macaulay ati awọn Alufa S. O. Ọmọnubi (De Love), E. A. Fagbayi, D. A. Oyewọle lati Arigbajo, J. A. Akinwande ati E. O. Fenwa lati Imẹko pẹlu awọn Ọgbẹni J. Oridọta, James Adebayọ, E. A. Jiboku, J. W. Dike, E. S. Ṣokunbi, Eman Babatunde ati Oloye A Bamgboye lati Owu Abẹokuta.

## Adajọ sọ ọlọṣa kan sẹwọn oṣu mẹfa

IBADAN.

LAIPẸYI ni Adajọ Kotu Kekere Ibadan sọ ọdaran kan Taibatu Abẹkẹ, ẹni ọdun mẹrinlelogun sẹwọn oṣu mẹfa nitoriti o jẹbi ẹjọ afole ati akole ti awọn ọlọpa ba à ṣe. Ọdaran na si ni on yio pe ẹjọ Kotẹmilorun.

Awọn ọlọpa sọ fun Adajọ na pe ninu oṣu kẹjọ ọdun ti o kọja yi ni ọdaran na lọ fole aladugbo kan, Clara Iya-Ṣẹlẹ ni 'Salvation Army School Road; Ibadan, o si ji awọn aṣọ diẹ ati ponun mẹrin (£4) owo silẹ.

Ọdaran na ni on ko fole Iya-Ṣẹlẹ, o si ni ti on ni gbogbo awọn ẹru ti nwọn ni on ji ti nwọn si ba ni ọwọ on.

## Awọn Musulumi Mọṣalaṣi Ọlọruntosin yan Lemọmu Titun

MUSHIN.

NI ọjọ Aiku ti ṣe ọjọ keje oṣu yi ni awọn Musulumi Mọṣalṣi Ọlọruntosin Mushin fi awọn enia meje jẹ oye ni ita gbangba Mọṣalaṣi. Eniti o we lawani fun wọn ni Alhaji Arikewuyọ. Orukọ awọn oloye mejeje na ni Alfa Raimi (Lemọmu) Tiamiyu Ọladẹinde (Ladani) I. O. Allara (Baba Adeen) Ibrahim Mumuni (Seriki), Akibu Alao( Arẹ) Salami Gbadebọ (Alafin) M. A. Sanni (Akọwe). Ọlọla F. OPaul Okuntọla sọrọ Apọnle nipa awọn oloye wọnyi, o si gba wọn ni iyanju lati ma a huwa rere si awọn ẹlẹgbẹ wọn.

Lẹhin imọran yi ni o bẹrẹsi pin iwe ẹri oye na le wọn lọwọ lọkọọkan. Onitirẹ ti Itirẹ Oba Lawal Afẹlẹlẹ, Ọlọla F. O. Paul Okuntọla, Mọmọ Isiba (Otun Ọba) Sadiku Sule ni nwọn ṣe alaga ọjọ na. Iyaafin Rashiri Iya Ibeji ni o si ṣe alaga obinrin.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeye ọjọna ni Adamu Animashaun (Serikin Musulumi) M. O. Ọlaogun, Wahabi Garuba ati awọn enia pataki pataki lati ilu okere. Imam Jamiyu Tairu lo ṣe adura ipari, gangan ati dundun dapọmọ aro bẹrẹsi dun, awọn oloye ati ebi wọn si ko ritiriti lọ si ile wọn. Oye na a mori o.



Awọn Oloye titun na niyi


# O rọrun to bẹ ẹ pẹlu

Esso AFIKUN

*O rọ awamọto lọrun*



Esso *nfun ni ni* **AFIKUN** *iṣẹ*

*O rọrun fun ẹngini rẹ*



Esso *nfun ni ni* **AFIKUN** *aabo*

*O rọrun fun apo rẹ*



Esso *nfun ni ni* **AFIKUN** *ere owo*

*. . . ma a lo* Esso *nigbagbogbo o ni* **AFIKUN** *ire!*



*Yika gbogbo agbaiye awọn onisowo ESSO ti nwọn wa funra ara wọn nfun ni ni AFIKUN iṣẹ daradara*

ESSO WEST AFRICA INC.

# A ko bi Owa Ilesha ba Oduduwa l'aiye

## LATI ỌWỌ ẸRUKOBODO-EKO



"ẸRUKOBODO"

* * *

Ololu, nlẹ o, ọmọ Odua!

INU mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi laye kiun lati ṣe alaye bi ao ti ṣe bi Ọwa Ilesha ba Ọba Oduduwa l'aiye fun awọn onkawe ti nwọn ti ka itan Ọwa Ilesha t'o jade lati ọwọ Alagba Olabọde Alajiki ninu "Irohin Yoruba" ti ọjọ kẹwa oṣu keji ọdun yi.

E dakun, nko fẹ ki gbolohun ọrọ okẹ iwe yi o jẹ ohun iyalẹnu rara, nitoripe, orisirisi itan l'ombẹ, bi itan aroṣọ ti mbẹ, bẹni, itan ohun ti oju ri ki o to di itan mbẹ pẹlu.

Ohun ti emi Ẹrukobodo nfẹ so ni asoye ni wipe, "Eni a bi ni bi, on ni Oyinbo npe ni Ability" ki owe na o jẹ ti ẹnyin onkawe.

Emi Ẹrukobodo jẹ ọkan ninu aromọdọmọ Ọba Oduduwa, Ọba aterere k'aiye, oriṣa t'o da ilẹ Ifẹ. Nitorina, itan bi Odu ti o da iwa ti ṣe da ilẹ Ifẹ, titi kan iru itan pẹ-pẹ-pẹ ti a npa yi ki yio jẹ ohun iṣoro fun mi lati pa yanju.

Itan to sọ wipe, a ko bi Ọwa Ilesha ba Ọba Oduduwa l'aiye lọ bayi:—Nigba iwaṣe, Ọba Oduduwa jẹ Ọba alakikanju ati ogboiya enia. Olọrun si fun un ni ọmọ to yanju bi, bi awọn ọmọ rẹ ti pọ to, Ọwa Ilesha ni abikẹhin awọn ọmọ rẹ gẹgẹbi Alagba Alajiki ti sọ o sinu itan rẹ ati wipe, Ọwa ni ọmọ to fi iwa igboiya ati awọ-ara jọ o pupọ ju awọn ọmọ rẹ yoku lọ.

Nitoripe, bi Ọba Oduduwa ti jẹ ogboiya Ọba to, kosi ọkan ninu awọn Ijoye nigba aiye rẹ ti o le pa aṣẹ rẹ da, ohun kohun ti o ba ro lọkan rẹ lati ṣe ni o nṣe ni, kosi ẹniti o le yi i pada, ni gbati awọn Ijoye igba aiye rẹ ro iru iwa ti o nhu si wọn titi, ti nwọn ko mọ ohun ti nwọn le ṣe, ni ọjọ kan, nwọn pe ara wọn jọ sinu Akodi Oloye Ọrunto, ti iṣe asiwaju awọn Ijoye Ile-Ifẹ. Oloye yi ni a npe ni Obalufẹ titi di oni oloni yi.

Nigbati nwọn pe jọ tan, nwọn ro larin ara wọn wipe, kini ohun to'tọ ti a leṣe fun Ọba wa ti ki i gba imoran Ijoye, ki o to ma a ṣe ohun t'o wu yi? Ninu ero wọn nwọn pinnu ero wọn s'ori wipe, kosi siṣe, bẹni kosi aiṣe, ohun to dara ati eyiti o bo Ọba ni aṣiri ni wipe, ki a pe e lọ sinu Iledi, bi a ba de bẹ,ao sọ ẹṣẹ t'o nṣe wa fun un, bi ko ba gbọ, a le da ṣẹriya fun un nibẹ pẹlu.

Gẹgẹbi ẹnyin onkawe ti mọ wipe, Iledi aiye igbana, o yatọ si tiwa ode oni. Ki ngma fa itan na gun, awọn Ijoye da ọjọ mẹdogun, ọjọ na si jẹ ọjọ Jakuta, nwọn ran Ẹmẹṣẹ kan ki o lọ sọ fun un wipe, ni ọọ mẹdogun loni, gbogbo awọn Ijoye rẹ nwọn nfẹ ri i ni Iledi. Lasiko ti awọn Ijoye Ile-Ifẹ nro ọrọ yi, a ko ti bi Ọwa rara, ṣugbọn, iya rẹ mbẹ ninu Afin gẹgẹbi ọkan ninu awọn Olori-Ọba Oduduwa.

Ki ọjọ ti awọn Ijoye da to o pe, nwọn ti lọ ra atori, nwọn si ko lọ pamọ sinu Iledi, ero okan wọn ni wipe, bi Ọba Oduduwa ko ba gba ohun ti awọn ba mba a sọ, nina ni awọn yio na a gẹgẹbi ofin Iṣẹdalẹ Iledi aiye igbana.

Nigbati ọjọ pe, ẹṣẹ gbogbo Ijoye, awọn bi: Oloye Obalufẹ, Olowa, Akogun, Jaaran ati awọn bẹẹ bẹ ti aiye igbana, ti pe ṣoṣọ sinu Iledi na, nigbati nwọn ri i wipe, ẹṣẹ wọn ti pe tan, nwọn tun ran Ẹmẹṣẹ kan, ki o loṣọ fun Ọba Oduduwa wipe, asiko na to, ati wipe, esẹgbogbo awọn Ijoye ilu lo ti pe sinu Iledi nitorina, awọn nreti rẹ o.

Kini Ọba Oduduwa gbọ bẹ e si, lẹsẹkanna lo dide, ti o gbe aṣẹ rẹ wọ, o doriko Iledi. Nigbati o de ẹnu ona Iledi ko s'opo kan ilẹkun iledi ki o to ra giiri wọle pẹlu igbe- rẹ, nigbati awọn Ijoye ri wipe, ko ṣe gafara kankan ki o to wọle ati wipe, oju ti o gbe wọle, o le aiti awọn inu bi wọn pupọ dẹpẹ, ti

(Wo oj- ...






Aworan oke yi ni ti igbati Oloye G. Akin Dẹkọ, nṣe ayẹwo iṣu kan nibi Ajọdun kẹfa Ifihan Ohun - Ọgbin ti awọn Ẹgbẹ Agbẹ Ifẹ ati Ilesha ṣe laipẹ yi.

* * *



Aworan oke yi ni ti igbati Oloye Ọlatunji Agunlejika, Lọja Oke-Bode nfi Ẹgẹ ti awọn Ẹgbẹ Agbẹ Ifẹ ati Ilesha fi da Oloye G. Akin Dẹkọ lọla de e lori nibi Ajọdun kẹfa Ifihan Ohun-Ọgbin ti nwọn ṣe laipẹ yi. Ọrọ ti nwọn kọ si ara Ẹgẹ na ni "OLORE AWỌN AGBẸ"

## OLUKỌ BI IBẸTA OBIRIN

IBINI.

LAIPẸYI NI Iyaafin Juliana Ọdẹrele Olukọagba 'Catholic School Ugboha, Beni" bi awọn awọn ibẹta obirin si ile-iwosan, Zuma Memorial Hospital', Irrua.

Ẹnikini ninu awọn ibẹta na wọn 3 lbs. 12 ozs.; ekeji wọn 3 lbs. 12 oz.; ẹkẹta si wọn 3 lbs. 9 ozs. Nwọn si wa ni alafia pẹlu iya wọn.


## ṣile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Ṣile kan pere ni owo rira rẹ, koro ẹgbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nisisiyi, ẹnikẹni le ni "ASPRO" ni ipamọ sowọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kọlu ọ tabi ẹbi rẹ. Mura silẹ.
Ra pakẹti "ASPRO" titun oni ṣile kan loni!

**'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO**


## Adajọ ni ki nwọn na Tisa lẹgba mejila

OTURKPO

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni Ọgbẹni Raymond Thague, Adajọ Kotu Kekere Oturkpo sọ fun ọdaran olukọ kan, Opiṭa Eka, ẹni ọdun mejidinlọgbọn ti o nṣiṣẹ ni ile-iwe Ijọba Ibile Badezi, pe ki iṣe iwe nikan ni awọn olukọ gbọdọ ma a kọ awọn akẹkọ, nwọn gbọdọ ma a kọ wọn nipa iwa rere pẹlu.

Adajọ na sọ ọrọ na nigbati o nṣe idajọ fun ọdaran olukọ na pe ki nwọn lọ na a ni ẹgba mejila: nitoripe o jẹbi ẹjọ iwa aidara ti o hu si ọmọ obirin kan ọmọ ile iwe rẹ t iko to ọmọ ọdun mẹtala. Awọn iwa buburu na ni pe o ba a lo p o ninu oṣu kọkanla ọdun ti o kọja yi.

## Iyaafin Nnoli bi ibẹta

LỌKỌJA.

LẸNULỌLỌYI ni Iyaafin Josephine Nnoli bi ibẹta, obirin meji ati ọkunrin kan si ile-iwosan. Alafia ni awọn ibẹta na ati iya wọn si wa.

# Hadj Imam Karimu şi Mọşalasi Ọladimeji

EKO.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Hadji Imam Abudu Karimu Bello si ẹka mọṣalaşi obirin Ọladimeji ti awọn baba isinku ologbe Iyaafin Hunmulihairi Ayilara Giwa Thompson kọ sinu mọṣalaşi Ọladimeji ni 1 Egerton Road l'Eko gẹgẹbi aṣẹ ati asọtẹlẹ ologbe na. Mọṣalaşi na tobi o si dara pupọ.

Hadji Imam Abudu Karimu Bello sọ ọrọ apọnle nipa ologbe na, o ni olore on ni o jẹ, olufọkansin ni i nigbati aiye rẹ ati pe on ni o fi on jẹ oye Lemọmu Mọṣalaşi Ọladimeji. O si ṣe akanṣe isin fun ologbe na. Lẹhinna ni o sọ nipa anfani pupọ ti o wa ninu Ẹsin Islam, o ni Ẹsin pataki pupọ ni Ẹsin na.

Ẹsẹ awọn Imam, Alhaji, Alfa, gbajumọ ati mẹkunnu ni o pe ṣoṣo si ibi aşeyẹ na, Hadji Imam Abudu Karimu Bello ati awọn baba isinku ologbe Iyaafin Hunmulihairi Ayilara Giwa ti apele orukọ rẹ njẹ Iya Alaṣo-oke nawo nara, nwọn si fi oriṣiriṣi onjẹ adidun tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun titi ilẹ fi ṣu.

## Awọn ọlọmọlanke mu ẹsun ọlọpa lọ sọdọ Ọba Kano

KANO.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni awọn ikọ ọlọmọlanke, nwọn fẹrẹ to igba enia, lọ ba Ọba Kano, Ọlọla Muhammadu Sanusi ni afin rẹ, nwọn si sọ ẹdun ọkan wọn fun un pe, nṣe ni awọn ọlọpa ti o nṣọ ọna mọto ma a ngmu awọn laini idi pataki kan.

Nwọn sọ fun Ọba na pe pọnun mẹrin mẹrin, owe iwe aṣẹ lati le ma a fi ọmọlanke ko apo gari ti yio fẹrẹ to mẹrinlelogun lẹkanṣoṣo ni awọn ti san.

Awọn ikọ na ni "sibẹsibẹ awọn ọlọpa ndaamu wa; nitori awọn ẹru ti o wuwo ti a nfi ọmọlanke ko" Ọba na si ṣe ileri fun wọn lati ṣe iwadi nipa ọran na.

## Adajọ sọ awọn ole meji sẹwọn oṣu mẹta-mẹta

BUKURU.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Alkali's Court), Bukuru ni ki awọn ọdaran meji, Gwajagbe Kano ati Friday Gandi lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹta mẹta: nitoripe nwọn jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba wọn ṣe pe nwọn lọ ji Malama Hawa Gawe ni oriṣiriṣi aṣọ obirin ti aropọ ye owo wọn jẹ pọnun mẹdogun (£15).

Ọga Ọlọpa (Corporal) Walter Lamunde sọ fun Adajọ pe nigbati Malama Hawa Gawe nrin irin-ajo lọ,o bẹ ọdaran Gwajagbe pe ki o wa ba on ṣe itọju iyara on ati awọn ohun-ini on, ọdaran si gba lati ṣe bẹ ẹ. Lẹhinti Malama Hawa Gawe ti lọ si idalẹ na tan ni ọdaran Gwajagbe si ti ranṣẹ pe ọdaran keji, Friday lati wa kole na.

---

*Ẹ ma a ka Iwe*
***IROHIN YORUBA***
***nigbagbogbo fun***
***irohin aladun***

---

# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

**Lati Ọwọ E. Alabi Thompson**

NINU ipọnju pupọ li awa o fi wọ Ijọba Ọlọrun—Iṣe Awọn Aposteli 14 ẹsẹ 22.

1. Olori Ijọ t'ọrun
L'ayọ l'awolẹ fun Ọ
K'Iwọ to de
Ijọ t'aiye
Y'o ma kọrin bi t'ọrun
A gbe ọkan wa s'oke
Pẹl'ero to n'ibukun
Awa kigbe
Awa f'iyin.
F'Ọlọrun igbala wa.

2. Bi a wa ninu 'pọnju
T' ankọja ninu ina
Ao yin 'fẹ Rẹ
To da wa si
T' o si nmu wa sunmọ Ọ
Awa ṣọpẹ, a si yọ
Ninu oju rere Rẹ
Ifẹ Mimọ
T' O fi yan wa
Y' o ṣe wa ni tirẹ lai.

**ITAN ORIN NA**

Ọgbẹni olorin ati ajikọdidun—Charles Wesley ni o kọ orin oke yi lati f'ẹdun pataki at'ayo Olugbala han: nigbati arakunrin rẹ kan wa ninu iwaiya-ija ati iṣoro. Şugbọn ju gbogbo rẹ lọ, Oluwa Olugbala fi iṣẹ iyanu rẹ han, O si gba a lọwọ gbogbo ifoiya ati ipaiya rẹ: nitorina o ni igboiya lati kọ ọ.




# ỌWA ILESHA

Lati Oju Ewe Kefa.

awọn na ko bu ọla Ọba fun un ki nwọn o to fi ẹsun rẹ siwaju rẹ, ki nwọn o to o ka ẹsun ẹṣẹ rẹ fun un delẹ tan. Ọba Odudua ti gbera lori aga ijoko rẹ, o fẹ mura lati ma alo, nibẹ ni awọn Ijoye ba ki i mọlẹ, nwọn ko atori bo o depo ti ara rẹ fi bo yankan-yankan, pẹlu irinu nla ni Ọba Odudua fi pada sinu Afin rẹ.

Ẹnyin onkawe ẹ maṣe sọ wipe, ọrọ mi pọ. Ibiti mo mba ọrọ bọ ni mo de yi. Gẹgẹbi mo ti so siwaju ninu itan yi wipe, ni gbogbo asiko ti a nsọ yi, a ko ti bi Ọwa s'aiye rara.

Lẹhin igbati Ijoye ti da ṣeriya yi tan fun Ọba Odudua, ni o to wa da'ṣẹ Ọwa, oyun Ọwa t'o wa ninu iya rẹ ki Ọba Odudua o to file aiye silẹ, a ko bi Ọwa l'oju Ọba Odudua rara.

Lẹhin ti Ọba Odudua ti file aiye silẹ tan ni iya Ọwa to bi i, o bi i sinu afin Odudua baba rẹ, nitoripe, elomiran ko ti i jo'ba ropo Odudua ki a to bi i. Ni ọjọ ti nwọn bi Ọwa, ni apa atori ti a fi na Ọba Odudua ninu Iledi ti han lara rẹ, okiki apa ara ọmọ kekere ti aṣẹṣe bi yi kan kakiri ilu ti o fi je wipe, t'ẹru t'ọmọ l'o sure lọ wo o ninu Afin.

### ON NA LO WA

Gẹgẹbi aṣa iṣedalẹ oyun ti Ọba ba fi sinu iyawo rẹ ki o to ku, tabi ki o to f'aiye silẹ, bi nwọn ba bi omo na, awọn Ijoye ilu ni nwọn ni lati wa, ko ọmọ na jade, ti nwọn o si sọ ọ l'orukọ t'o ba wu wọn.

Nigbati ọjọ a ti sọ orukọ ọmọ tuntun ti iyawo Ọba Odudua yi bi pe, ẹsẹ gbogbo awọn Ijoye lo pe biba sinu afin, nigbati nwọn ṣe etutu idile Ọba tan, Oloye Ọruntọ ti ise aṣiwaju, tabi Adele Ọba Ile-Ifẹ dide, o gbe ọmọ na lọwọ, o nfẹ fun un l'orukọ, nigbana ni Oloye Lọwa aiye igbana dide, o sọ fun Ọruntọ wipe, orukọ ọmọ yi, ko si ninu ohun t ia nwa lọ titi, ẹ wo o, tabi ẹ ko ri apa atori ọjọ kini lara rẹ ni? Kosi orukọ miran ti a tun le so ọmọ yi t'o ju "ON NA L'OWA" lọ. Bayi ni gbogbo Ijoye ati awọn enia pataki-pataki to peju-pesẹ s'afin Ọba Odudua l'ọjọ na fi sọ ọmọ abikẹhin Odudua ni "ON NA LO WA", orukọ yi ni awọn ẹgbẹ rẹ nigboro Ile-Ifẹ, l'aiye igbana ge kuru, ti nwọn fi npe ni ỌWA.

Bi Ọwa ti fi iwa rẹ jo Odudua to, lati kekere rẹ ni o ti bẹrẹ si huwa akọ s'awọn ọmọ wẹwẹ ẹgbẹ rẹ ti nwọn nṣire pọ ni igboro Ile-Ifẹ titi o fi fi iya rẹ silẹ se atipo lọ ibiti a npe ni Ilesha di oni oloni yi.

Ni wara nṣẹṣa ti Ọwa kuro nile Ifẹ, o lọ joko ti baba kan ti ki igbin ohun miran sinu oko rẹ bikoṣe ila, gẹgẹbi Alagba Alajiki ti sọ ọ sinu itan rẹ, on pẹlu baba yi ngbe pọ, nigbati o pẹ ti Ọwa ti fi iya rẹ silẹ ni Ile-Ifẹ, ni iya rẹ bẹrẹ si wa a kiri, ko pẹ ju ti iya rẹ ti nwa a kiri ki o to gburo rẹ wipe, lọdọ baba onila kan lo wa.

Kini iya rẹ gbọ bẹ ẹ si, kosopo ṣe meji, on na kuro ni Ile-Ifẹ, o lọ ba ọmọ rẹ, nigbati o de ọdọ ọmọ rẹ, (Ọwa) ko si isẹ meji ti iya Ọwa nṣe bikoṣe wipe, o mọ Isa (eyi ni ikoko kekere ti nwọn nfi pọn omi). Bi iya Ọwa ba mọ ọ tan, a ko lọ si oju ọna, a si ma a ta wọn fun awọn ero to'ba nkọja lọ, nigbati o pẹ ti iya Ọwa ti nta Iṣa yi, okiki rẹ kan ka agbegbe ilu t'o yi wọn ka, eyi mu ki awọn ero ti nwọn lọ ra Iṣa yi sọ oke ti Ọwa ati iya rẹ ngbe ni. Ọke-Iṣa. Oke-iṣa yi wa larin adugbo ilu Ilesha ti orukọ na ko si yi pada titi di oni oloni yi. Itan yi lo fi han emi 'Ẹrukobodo' wipe a kọ bi Ọwa ba Ọba Odudua l'aiye. Ẹniti o ba tun ri sọ si itan yi ki o sọ jade, nitori, orişirişi itan l'o mbẹ nilẹ Yoruba.

Emi "Ẹrukobodo" ti mura tan lati sọ itan bi nwọn ti şe da ilẹ Ile-Ifẹ ati bi Odudua ti şe rọ si Ile-Ifẹ ati bi o ti şe pada s'ajule ọrun,nitori pe, a ko bi Odudua, beni ko ku rara.

Olotu, oju o fẹra wọn ku o.







# AWORAN ONITAN



# Akiyesi Awọn Awo Irawọ nipa Ọjọ-ibi

**AWỌN nkan wọnyi ni yio ṣẹlẹ larin ọsẹ yi lati February 21st si February 27th, 1960.**

## CAPRICORN
**(Dec 21st-Jan 19th)**

Bibọ si ibi ati si ohun yio pọju fun ẹ. Ayipada yio wa fun lori gbogbo nkan. Wa a si ni owo lọwọ.

## AQUARIUS
**(Jan 20th-Feb 18th)**

Wa a ni awọn ọrẹ miran ati awọn ẹgbẹ miran. Awọn ti o mba a lo ko ri imọlẹ tabi ko ni imọ o si ni lati fi lakaye ma a ba wọn lo.

## PISCES
**(Feb. 19th-Mar. 20th.)**

Wa a ri iṣoro kan boya nipa ọran ara inu ile tabi nkan inu ile ni. Wa a tun awọn ọran miran ṣe.

## ARIES
**(March 21st-Apl. 20th)**

Ariyanjiyan kan yio mu ẹ binu si ẹnikan. Owọ rẹ yio di pupọ, wa a si ni lati ma a lo ọgbọn-ori ati laakaye, wa a si turaka pupọ si awọn enia.

## TAURUS
**(Apl. 21st-May 20th)**

Ọpọlọpọ ohun ti o ba bẹrẹ lati ṣe nigbati ọsẹ yi ba fẹ pari yio yọri si ire. Bi o ba ṣẹṣẹ bẹrẹ wọn, wa a ri ọpọlọpọ atako.

## GEMINI
**(May 21st-June 20th)**

Awọn eto ti o ba nṣe yio fẹ daru, maṣe daamu nipa wọn, ṣa fi ara balẹ. Maṣe ja nipa ọran owo (money.

## CANCER
**(June 21st-July 20th)**

Maṣe fi awọn ọran pataki jafara. Aifi wọn jafara ni yio ṣe ẹ ni anfani. Larin meji ọsẹ yi awọn ohun ti yio ṣe ẹ ni anfani yio yọ si lọwọ. Ma a lọ ṣe ere idaraya larin ọsẹ yi.

## LEO
**(July 21st-Aug. 21st).**

Wa a ri igbadun. Aini suru le jẹ k'o padanu iṣẹ ti o ni aseko ti o mbẹrẹ rẹ ati aseko ti o njiṣe.

## LIBRA
**(Sept. 23rd-Oct. 23rd)**

Gbogbo nkan yio lọ fun ẹ dada, ero rere rẹ yio si yọri si rere.

## SCORPIO
**(Oct. 24th-Nov. 22nd)**

Sọ ara rẹ nipa a nkọwe si ara ẹni tabi nipa ki o lọ ki enia tabi ki nwọn wa ki ẹ laseko yi. Bibẹkọ, wa a ri iyipada ti yio yatọ patapata si awọn eto ti o ti ṣe silẹ.

## SAGITTARIUS
**(Nov. 22rd-Dec. 20th)**

Nipa ọran anọ tabi awọn ara adugbo rẹ, nwọn ntan ẹ jẹ ṣugbọn nwọn ko ni le ba awọn ohun pataki ti o ni ifẹ si jẹ.

## Adajọ sọ ẹniti o ji oku ni £130 sẹwọn oṣu mejidinlogun

IBADAN.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere Onireke sọ ọdaran kan Lasisi Akande, ẹni ọdun mẹtadinlogoji ti awọn ọlọpa pe ni ẹniti ndibọn sẹwọn osu mejidinlogun, nitoriti o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o ji oṣiṣẹ Reluwe kan ti o ti ku ni pọnun mejileladoje (£132.)

Adajọ na da Regina Okebukọla, ẹni ọdun marundinladọta ati Raji Fanti, ẹni ọdun mọkandinlogoji ti awọn ọlọpa mu pẹlu ọdaran na silẹ, o ni wnọn ko jẹbi

## Obirin ti o ge wọn je fi £5 tanran

ONITSHA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejọ oṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere Onitsha ni ki ọdaran obirin kan, Violet Okoye fi pọnun marun tanran tabi ki o lọ s'ẹwọn oṣu kan nitoripe o jẹbi ẹsun ija ti awọn ọlọpa ni o ba Victoria Ọba ja ti o si bu ti je bi aja.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ro ni pe ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹta osu yi, ni 1, Oranye Street, Onitsha, ija bẹsilẹ larin ọdaran yi pẹlu Victoria dipo ki ọdaran yi fi owọ ja a ehin lo da de e lẹhin ati lejika ti o si da ogbẹ si lara.



**Aworan oke yi ni ti igbati Oninọmba kan nkọ nọmba fun ọmọ-ọwọ kan, Bọlatito Ojo, ki arun igbona ma ba a le ba a ja. Ọ jẹ ọkan ninu awọn ẹgba a ọmọ-ọwọ (2,000 babies) ti nwọn gbe wa si ibi eyẹ Ayẹwo Ilera awọn ọmọde keji ti nwọn bẹrẹ laipẹ yi ni Eruwa lẹba Ibadan. Ọgbẹni C. A. Williams, Akọwe Iriju Amojuto Eto Ilera ati alafia ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun ni o ṣi ipade na.**




# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Adajọ sọ ẹniti o na ale iya rẹ s'ẹwọn oṣu kan

UYO LẸBA CALABAR.

LAIPE yi ni Ọgbẹni O. Inko-Tariah, Adajọ Kotu Kekere Uyo, so ọdaran kan, Nyong Jonah, ẹni ogun ọdun, sẹwọn oṣu kan nitoripe o jẹbi ẹjọ lilu ti o lu ale iya rẹ, Willi Akpan ni Ewet l'ẹba Uyọ.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ro ni pe ale iya rẹ yi ba ọdaran na wi fun ilẹ baba fun awọn ọkọ wa ti o ngbe rẹ ti o gbe ta lai gba aṣẹ lọwọ ẹbi rẹ yoku. Eyi bi ọdaran na ninu to bẹ ẹ gẹẹ ti on pi ki ale iya on yi yara kuro ninu ile on, ṣugbọn ki o to kuronibẹ o ti ko igbaju igbamu bo o, o si tun jan an mọlẹ, o si dọgbẹ si i ni oju ọtun. Nigbati ọdaran na ro'jọ tirẹ, o ni irọ ni awọn ọlọpa pa mọ on, on ko fi ọwọ kan an rara.

## Awọn Ojowu Obirin meji ja fọ iṣasun ọbẹ kan

ENUGU.

LAIPE yi ni awọn ọlọpa ko awọn ọdaran obirin meji kan, Ethel Nwizor, iyawo lebira Reluwe kan ati Alice Etim, iyawo awamọto takisi kan, wa si iwaju adajọ Kotu Kekere Enugu pẹlu ẹsun pe nwọn ja nitori ọkunrin ọlọkunrin. Nigbati nwọn ka ẹsun na si wọn leti, nwọn ni awọn ko jẹbi.

Awọn ọlọpa ni, ninu ẹjọ ti Ethel ro fun awọn, o ni on gbọ wipe Alice mba on jẹ kakiri lọdọ akọwe awọn Oyinbo U.A.C. kan ti o nfẹ yan an on lọrẹ. Ni ibiti nwọn gbe nyanju ọrọ yi larin ara wọn nibiti nwọn gbe nda ina onjẹ lọwọ ni ọrọ na ba di ija ti nwọn si ja fọ iṣasun ọbẹ ti Alice ṣẹṣẹ se tan fun ọkọ rẹ. Awọn ọlọpa ni awọn yio ko afọku iṣasun na wa han adajọ ni ipari oṣu yi ti nwọn fẹ bẹrẹsi ro ẹjọ na.

## ỌLỌPA OBIRIN KU

PORT HARCOURT.

NI arọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Omidan Lucy Batta, Ọlọpa Obirin (second class constable) ara Eket in Ipinlẹ Kalaba ku si Ile-iwosan Ijọba Port Harcourt.

## Adajọ sọ ẹniti o pe ara rẹ ni ọlọpanu si ẹwọn oṣu mẹfa

OWERRI.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere Owerri so ọdaran kan, Emmanuel Ofoha ti o nṣiṣẹ awayanrin (sand digger) si ẹwọn oṣu mẹfa: nitoriti o jẹbi ẹjọ 'onijibiti' ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o fi ara rẹ pe ọlọpanu o si fi agbara ni ki awamọto akẹrọ kan, Christian Igbonu fun on ni pọnun mẹta (£3) nigbati o ti ka awọn ero ti o wa ninu mọto na tan.

## *Adajọ ni ki nwọn lọ na ọmuti kan ni ọgọrin ẹgba*

BAUCHI.

LẸNULỌLỌYI ni Malam Babaji, Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Alkali's Court) ni ki nwọn lọ na ọdaran kan, Hassan Bikili ti o sọ fun Adajọ na pe on ko le galai mạ mu ọti ni ọgọrin ẹgba nitoriti o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o lọ mu ọti yo pupọju, o si mbu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu. Adajọ na sọ fun ọdaran na pe, Alkurani Mimọ kọ o fun gbogbo Musulumi lati mu ọti.

## Awọn lebira meji ku sẹnu iṣẹ

KADUNA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn lebira meji Ba'hago Dal 'hartie ati Tabarchi Iburu ku lẹsẹkẹsẹ nigbati iyanrin ti o wa ni ẹgbẹ eyi ti nwọn nwa (digging) lọwọ ya mọ wọn lẹsẹ ti o si bo wọn mọlẹ patapata lojukanna, lẹba St. John's College, Kaduna.

Awọn lebira marun ti nwọn mba wọn ṣiṣẹ pọ lọjọna moribọ ninu ijamba na nwọn ko ṣeṣe rara, nwọn si ti gbe oku awọn lebira na ti o ku lọ si lakulaku fun ayẹwo.

## Akanbi gbe Ayisatu ni iyawo alarinrin

ỌFFA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu kini ọdun yi ni Ọgbẹni Abudu Lasisi Akanbi, ọmọ Bello Ile Abẹsingọgan, Ita Erin Offa gbe Omidan Ayisatu Ajiri, ọmọ Buraimọ Alao, Ile Eso Oke ni iyawo alarinrin, ọkọ iyawo ati awọn ẹbi rẹ, awọn Ọgbẹni Oseni Akanni (carpeter), Musitafa (barber), Tiamiyu Ajimati, Alimọtu ati Limọta nawo-nara nibẹ.

Awọn ọrẹ ọkọ iyawo na, awọn Ọgbẹni Amuda Gold Smith, Ramọnu Anifowoṣe, Muritala Adegboyega Lawal Muritala Tailor, Buraimọ Ọdẹ ati Muritala Raji Awudere dabira ni ibi aṣeyẹ na, nwọn si na ọpọlọpọ owo. Aṣeyẹ ọjọ na dun o laririn, irohin ko to afojuba ni.

Ki Ọlọrun fi ire kari ki O si fun iyawo ati ọkọ rẹ ni aridunnu ọmọ ọkunrin ati obirin.

Ire a kari o.


Yan ọrẹ kan!

fi siga GALLEON

TI NAIJIRIA NFẸ Ş'ALEJO

o ndun bi olowo-nla

... owo rẹ si kere pupọ

kọbọ kan fun ẹyọ kan

1/8 fun 20






IROHIN YORUBA

# Ẹka Ẹgbẹ Alakukọ ni ki Azikiwe fi ipo Agba oselu silẹ

## OGBOMOSHỌ PARAPỌ

(Lati oju ewe kini)

Yoruba fun lilo awọn ọmọ ile-iwe kakiri Ipinlẹ Iwọ-Orun, nwọn si dupẹ lọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun fun awọn ile-iwe ati nkan idagbasoke ilu ti nwọn ti pese rẹ si Ogbomoshọ, ki Ijọba na si jọwọ ba wọn mojuto ilọsiwaju wọn dada.

**OLOYE AKINTỌLA FESI**

Oloye Akintọla si fesi si ọrọ aponle awọn Ẹgbẹ Ogbomọshọ Parapọ na pe: Lotitọ ipo ola, ipo alasẹ tabi aye ipo ti nwọn ba fi danilọla jẹ nkan pataki, ṣugbọn gbogbo rẹ ni o ni opin. O si ṣe ikilọ fun awọn enia na pe, ki ẹnikẹni maṣe lọ ipokipo ti o ba wa ni ilokulo, o ni, "Ki iṣe iṣe ipo ti enia ba ni laiye ni o jẹ nkan pataki bikoṣepe obi oluwarẹ ba ti nlo aye na si". Nitorina, o rọ gbogbo enia pe, ki nwọn ni ifọwọsowọpọ lati ṣiṣẹ fun ire ati anfani gbogbo enia jakejado pinlẹ Iwọ-Orun ati Apapọ Naijiria. Oloye na si sọ pe, on tọrọ adura gbogbo wọn ati ifọwọsowọpọ wọn lori iṣẹ ribiribi ti o wa ni ejika on lati ṣe fun anfani gbogbo enia yi.

## *Adajọ ni ki ọmuti kan lọ fi £2 tanran*

BAUCHI.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ kekere (Junior Alkali's Court) ni ki ọdaran ọdọmọdekunrin kan, Sheriff Moutari Kano lọ fi ponun meji tanran tabi ki o lọ ṣe ewọn oṣu kan nitoripe o jẹbi ẹṣẹ ti awọn ọlọpa ka si lorun pe o huwa rudurudu ti o le ba alafia ilu jẹ. Adajọ na si da a silẹ, o ni ko jẹbi ẹṣẹ keji ti awọn ọlọpa ni o da pe o mu ọti: nitoripe ọdaran na sọ fun Adajọ pe on ki i ṣe Musulumi, o ni Kiriyo ni on nṣe (Ẹṣẹ ni fun Musulumi lati mu ọti ni Bauchi, ṣugbọn ki iṣe ẹṣẹ fun Kiriyo lati mu u).

Ẹjọ ti awọn ọlọpa rọ nipe ninu ọsẹ keji ti o kọja yi ni ọdaran na bẹrẹsi pariwo ti ko tọ rara ti o si bi awọn enia miran ninu lẹhinti o ti mu bia yo tan. Ọdaran na si sọ f'Adajọ pe alejo ni on jẹ ni ilu Bauchi ati pe on kọ si mọ pe Ijọba ko gba enia laye lati sọ ohunkohun ni Bauchi gẹgẹbi Ijọba ti ṣe gba enia laye ni Kano lati sọ ohun ti o ba fẹ sọ.

(Lati oju ewe kini)

wọn (Ipinlẹ Ariwa), ni o wa yẹ ki o ṣe Alakoso Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria?

Nwọn ni gbogbo enia si ti mọ eto Ijọba wọn pe eto ti kọ ba Ijọba Ọlaju ode isisiyi mu ni ati pe, iru iya ti nwọn fi jẹ awọn ọmọ Ẹgbẹ NEPU wo dara rara lati fi wọn silẹ ninu ijiya laijẹpe nwọn da wọn silẹ ki Ẹgbẹ Alakukọ to sowọpọ pẹlu wọn lati ṣe Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ati wipe awọn si wa pẹlu Ẹgbẹ NEPU lati ba wọn gbọn iya-jijẹ na nu.

Nwọn ni awọn woye pe abuku kan tale ẹgbẹ oṣelu awọn (NCNC).

Nigbati Ọgbẹni Harold McMillan, Alakoso Ijọba Gẹẹsi wa si Ile Ipade Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria 'biti awọn aṣoju Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ati Igbimọ awọn Agba-Oṣelu fi ni ipade papọ, ti o jẹ wipe Alaga Ipade Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria nikan ni o sọrọ ti o kan jẹ wipe nṣe ni Dọkita Azikiwe, Olori Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) nwo iran ṣa a ni titi ti nwọn fi setan nwon ni abuku gba a ni eyi jẹ fun ẹgbẹ oṣelu awọn NCNC).

Nwọn ni ohun ti awọn ri pe o tọ fun Olori Ẹgbẹ Alakukọ ni pe ki o wa ninu Ile Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria, ki o si yan awọn iriju Igbimọ tirẹ ti yio ma a ba a da imọran gẹgẹbi Alakoso Ijọba ti yan awọn Minista tirẹ ti o mba a da imọran. Nwon ni awọn fẹ ki gbogbo awọn Minista ti o ba jẹ ti ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) maṣe ba wọn lọwọ ninu lilo si Londonu lọ ba wọn ṣe ipade ti awọn Oṣelu Naijiria tun nfẹ lọ-ṣe.

Nitori awọn rọ pe, ẹto ti yio gbe fun awọn Gẹẹsi, ati bi awọn enia wọn ti o nṣiṣẹ labẹ Ijọba Naijiria yio ti ṣe ni irorun ati ifẹsẹmulẹ ninu iṣẹ Ijọba nigbati a ba gba Ominira tan ni nwọn fẹ ba wọn da imoran rẹ ninu ipade na. Nwọn si tun fi kun ọrọ wọn pe, awọn ko faramọ awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakuko ti o nṣe iranlọwọ fun Ẹgbẹ Olomi (NPC) ti nhu iwa ibinisubu lati fi gba ola ati agbara Ẹgbẹ Oṣelu Alakukọ nitori ti ohusogba ajara rẹ ko si nibẹ.

## AKIYESI FUN ONKAWE

**Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin onkawe ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o maa kọ o taara si ile iṣẹ rẹ ni :**

Amalgamated Press Ltd.,
5/7, Apongbọn Street,
P. O. Box 163, Lagos.



Eyi ni aworan awọn ogunlọgọ enia ti o to si ojude Afin Buckingham nigbati Ọba 'birin Gẹẹsi nrọbi ti nwọn nfẹ gbọ irohin bibi-ọmọ na ti o bi ni ọjọ Ẹti ọjọ kọkandilogun oṣu yi. Nwọn si wa nibẹ titi nwọn fi ṣe ikede pe Ọba 'birin na bi ọmọkunrin kan ṣikẹta awọn ọmọ meji ti o ti bi tẹlẹ.


**Nihin ni IRORA rẹ wa**

*Iwe aworan yi ni o fi ibiti aisan gbe wa lara han nigbati awọn oree inu rẹ ko ba ṣiṣẹ deede*



**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**

nṣe iṣẹ atunṣe oree inu taara ni lati ti oro inu ti o ngmu irora wa jade

Lẹhin wakati diẹ ti o ba ti lo "De Witt's Pills" tan itọ rẹ yio mu awọ miran wa. Eyi ni ẹri pe oogun ti o yanilẹnu yi ti bẹrẹ si ṣiṣẹ niyẹn, o nda LAKUREGBE, ARA-RIRO, ẸHIN-DIDUN ATI GBOGBO IYỌNU APO-ITỌ DURO





**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**


Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd. 5/7, Apongbon Street, Lagos (Editorial) and Advertisement Office) Telphone 23679. 23676. Fun owo "Irohin Yoruba" ọdun kan. Eko sile mejo ati kobo mejo (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu S. M. [illegible] 1 Idumagbo Street Idi-Oro